ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV N0 829 LAGOS SATURDAY JULY 21, — JULY 27, 1962

# Woli Kan Ba Obinrin Lo Ni Sosi

## Gbogbo Ijo Tuka M o Lori L'oke Foko

IBADAN—A gbọ ju igba silẹ ni awọn ara adugbo ti nwọn npe ni Agbokojo, Fọkọ ati Gẹgẹẹ ti nwọn ri obinrin alarede kan ti o lọ woli onisẹ Ọlọrun kan ti nwọn pe ni Josiah mu ni papankoko ninu ile adura laipẹ yi, sugbọn nigbati nwọn bere wipe kinni o de Woli ni o jẹbi, nitoripe o tu obinrin na si ihoho niuu Ṣọsi, o si ba a lo.

Bayi ni a gbọ irohin na lati ọwọ onirohin wa ni Ibadan, arabinrin kan ti nwọn npe ni Filicia Ogunrẹmi lọ si ile adura woli Josiah fun adura, nigbati o nlọ, o ra abẹla diẹ lọwọ gẹgẹbi awọn obinrin ijọ Serafu na ti ma nṣe ti nwọn ba fẹ ki nwọn ṣe adura pataki fun awọn nitori abiku tabi nitori agan

Ni ọjọ ti ọrọ yi ṣẹlẹ gbogbo awọn ijọ ile adura Josiah ni o pe si ibi ti o pe ni Ṣọsi na ti "ẹmi" ngbe wọn sanlẹ, ti olukuluku nsọ iran ti nwọn ri. Lẹhin eyi Woli Josiah paapa ni on riran kan pataki si arabinrin Filicia, on si ni lati ṣe adura pataki fun un, nitorina ki awọn ijọ yoku ma lọ si ile wọn.

Lẹhin igbati awọn ijọ yi lọkunrin ati lobinrin ti kuro nibẹ, ti woli yi ti tilẹkun, ti o bẹ'ẹ adura pataki na ni a gbọ wipe "aiperi" wọ ọrọ wọn ti arabinrin na si lọ mu papankoko; awọn ọlọpa ni nwọn gba ẹwu woli na lọwọ arabinrin Felicia ti nwọn si ko wọn lọ si ile-igbẹjọ awọn ọlọpa.

Lati igba na ni gbogbo awọn ijọ woli Josiah ti fi akee kọri, nwọn ni awọn ko lọ si ile adura rẹ mọ nitori oni-pọnsan-pọnsan ni.

Advt. N0. 109

# IKEDE

### OWO ATIJỌ TI WEST AFRICAN CURRENCY BOARD

Lati ọjọ kini oṣu July, 1962, eyiti iṣe oṣu keje ọdun yi, gbogbo owo atijọ patapata ni pepa kọrẹnsi ati ṣile pẹlu owo wẹwẹ miran bẹ ti West African Currency Board ti kuro labẹ ofin ni jake jado ilẹ Nigeria. Owo yi ko ni ṣe na mọ fun sisan gbese tabi ki o wulo fun tita tabi rira ọja ni ṣọpu ati ni ọja. Ṣugbọn owo wọnyi ṣi ni iye lori ati wipe ẹnyin si le ṣe paṣi-parọ wọn ni gbogbo Bank.

Lati ran yin lọwọ, Central Bank ti Nigeria ti ṣe eto pẹlu gbogbo Bank pe ki wọn ma ṣe dẹkun lati ma ṣe paṣi-parọ owo pepa kọrẹnsi ti atijọ l'ọfẹ fun awọn enia titi di ipari oṣu September, 1962, ti nṣe oṣu kẹsan ọdun yi ati fun owo ṣile ati awọn isọngbe rẹ titi di pari oṣu December, ti nṣe ipari ọdun yi.

Nitorina a bẹ gbogbo yin patapata lati mu owo atijọ ti o mbẹ lọwọ yin lọ si Bank ti o ba sun mọ yin ki Ẹ lọ ṣe paṣi-parọ wọn l'ọfẹ si owo Nigeria titun ti Central Bank fi si ode ni iwọn ọdun mẹta sẹhin. Ẹ ma ṣe jaf'ara.

Gbogbo ẹniti ko ba parọ owo atijọ ọwọ rẹ si owo Nigeria titun titi asiko ti a fi silẹ fun yin ba fi pari yio san owo fun Bank nigbati o ba fẹ ṣe paṣiparọ owo atijọ rẹ lẹhin ọjọ wọn yi.

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
LAGOS.

**W. A. TIBBLES**
GENERAL MANAGER

# Awo Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 20)

Ọkan rẹ kun fun orişirisi erọ ti pe ọrọ ede aiyede ti yio bẹ silẹ suru ni ki o mu ki o ba le yọri si rere.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Şọra pupọ lori inawo lose yi, ki o si yera fun awọn obinrin nitori wahala airo tẹlẹ.

ARIES (Mar 21–April 20) Ẹniti o ba mba naja ni ki o wo ninu ọsẹ yi, ki o mọ ko irin meji bọna lẹkan. Ati ọkunrin ati obinrin ni re rẹ wa lọdọ wọn.

TAURUS (April 21–May 20)

Şọra ki o ba mọ padanu owo, ki o lo ọgbọn ati oye fun awọn nkan abami ti o ba ri ninu ọsẹ yi. Ọjọ Monday a dara fun ọ pupọ.

GEMINI (May 21–June 21) A mbọ sihin, a mbọ sọhun wa fun ọ ninu ọsẹ yi, gbogbo wahala rẹ ko si ni jẹ ofo. Gba imọran lọwọ agbalagba, ki o mọ si şe jarọ.

CANCER (Jun 22–July 23) Maşe fi akoko jafara rara; ninu ile rẹ ti o ngbe nwọn a ba ẹ şe gbolohun-asọ, suru ni ki o mu. Ọjọ Monday dara fun o.

LEO (July 24–Aug 22) Amọdi ferẹfẹ kan wa fun ọ, nitorina ki o tọ dokita rẹ lọ. Ninu kila-kilo na wa ru u ye.

VIRGO (Aug 23–Sept 23) Nwọn a pe ọ si ibi ipade pataki kan, ki o sọ ẹnu rẹ ki o mọ nkan ti wa sọ nibẹ.

LIBRA (Sep 24 -Oct 23) Irawọ rẹ ni ọsẹ yi a mọ ti ẹ sihin sọhun nitorina ki o şọra ki o mọ nkan ti o nşe.

SCORPIO (Oct 24–Nov 22)

O fẹran a tun pinpin nkan iu, eleyi si le jẹ ki o şi nkan şe lọsẹ yi, nitorina ki o kiyes'ara.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Maşe nkankan ti n mu arẹ ba ọ lọjọ Aje (Monday.) Ọrẹ ti o ba gbẹkẹle ni ki o fi aşiri rẹ han. Ki o şọ'ra pẹlu ọrọ isọlẹnu kan lọjọ Isẹgun (Tuesday.)

CAPRISCORN (Dec 23– n 12)

Wa şe alabapade ori-rere kan ni airotẹlẹ, şugbọn ki o tọju ara rẹ daradara ki ajinde ara le mọ jẹ fun ọ.

# Oshuntokun Ni A G Ko Se Ire Fun Ekiti

## Obinu Fi Egbe Sile

IBADAN—Lati igbati ruke-rudo ti de si awọn ọmọ ẹgbẹ Afenifere (AG) ni ilu Ibadan, ogunlọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn ti binu fi ẹgbẹ na sile nisisiyi. Ọkan ninu wọn ni Ọgbẹni Joseph Oduọla Ọshuntokun, ẹniti nwọn şeşẹ da silẹ ninu ahamọ apapandodo.

Ninu iwe kan ti o kọ si baba ẹgbẹ na, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ wipe on ko şe ẹgbẹ mọ, Ọshuntokun ni lati igbati on ti de inu ẹgbẹ na on şe akiyesi wipe gbogbo nkan rere ti awọn ẹgbẹ na fẹ şe fun ilu Ekiti ni Oloye Awolọwọ nta pa. O ni awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun şe eto lọdun kan wipe awọn yio yọ ọda si awọn oju ọna mọto ti nwọn jẹ pataki ni agbegbe Ekiti. Oloye Awolọwọ na ni o tun ta wọn pa.

Ọshuntokun ni ẹnikan ninu awọn ẹleri on ni Oloye Ọdẹbiyi nipa ọrọ oko koko (cocoa) kan ti nwọn ni awọn fẹ da si agbegbe Ekiti ati ni ilu awọn Ẹgbado ti Oloye Awolọwọ dari işẹ na si ibomiran.

## Iro Nla

Ninu esi iwe ti o jade ni ijẹta lati ile awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A G) na, nwọn ni irọ nla ni Ọshuntọkun pa ninu gbogbo awawi ti o sọ silẹ. Nwọn ni Ọke aimọye owo ni awọn Ijọba Iwọ Orun na si oju ọna ilu Ekiti bi ọna - mọto Okemẹsi, Igbaraodo, Ilawẹ, Ikẹrẹ, Ọtun, Aramọkọ ati bẹẹbẹ, laiye ijọba Awolọwọ.

Nwọn ni nitotọ ni Awolọwọ ti fẹ yọ Ọshuntokun kuro ninu ẹgbẹ nitori ọrọ owo kan ti o fi ọna ayikọrọyi ya lọwọ Ijọba lati ma fi şe işẹ mọto, on pẹlu awọn ti nwọn jọ da ẹgbẹ işẹ mọto na silẹ.

# OMO NIGERIA TI O NKO ISE ILE KIKO



Aworan oke yi ni ti Ogbeni Felix O. Ibru, omo odun merinlelogun ti o nko ise ile kiko ni ilu Oyinbo. Odomokunrin na gba ebun fun aworan oja enia-dudu ti o se.

# Eko Akete ILE OGBON (6)

**( Lati owo Olalekan Onatade )**

## Lagos Stores

GẸGẸBI mo ti fi ye nyin ninu iwe itan mi ti ọsẹ ti o kọja, ile-itaja ti o tun jẹ pataki lẹhinti a ba ti kuro ninu sọbu awọn India yi ni ti awọn Faranse ti mo ti sọrọ wọn siwaju ati A. G. Tangalakis, ki a to wa de ile kan ti nwọn npe ni Manchester House. Ti o ba fẹ gba Ẹhingbẹti (Marina) wọ ile itaja awọn Kingsway Stores loni, ibẹ na ni wa gba wọ ile atijọ yi. Boya o le fẹ bere wipe awọn Oyinbo onisowo wo ni nwọn wa nibẹ nigbana, awọn ni LAGOS Stores, awọn Oyinbo ANKURI.

Awọn onisowo Lagos Stores yi lo da ibisẹ Kingsway Stores silẹ ni 1930 nigbati gbogbo awọn Oyinbo onisowo kan da owo pọ ti a si mọ orukọ wọn ni U.A.C. di ọjọ oni. Nibiti nwọn kọ si ile itaja Kingsway Stores na si ni o gbe ile awọn Oyinbo West African Drug Company ni Ẹhingbẹti nisisiyi.

Nigbati awọn Oyinbo yi bẹrẹsi ṣọbu Kingsway yi, aṣọ-wiwọ awọn Oyinbo, bi bata, ṣọọti (shirts) sokoto-bọsi-kọnọ (ready made) ati ẹwu (coat) pẹlu tayi (tie) ti o gbadun ni nwọn nta nibikibi ti nwọn ba gbe wa bi Ibara l'Abẹokuta, 'Gbagi in Ibadan ati ni Sabongari Kano. Ti o ba si se akiyesi wa ri wipe inu ile awọn Oyinbo oniwalaa ti nwọn han ọrọ yi si; "ANKURI MAGANI DUNIAN", ni nwọn ni lati wa nibikibi ni Nigeria nigbati nwọn daa silẹ.

## Awon Elegbogi

Lati ran awọn alaisan lọwọ lati mọ tete ri egbogi ti ko ba si nile awọn oni'wosan ra ni nwọn ṣe da ile tita oogun West African Drug Company l'Eko silẹ; ni Customs Street leti ile sọbu awọn ọlọpa atijọ (Central police station) nibiti Central Bank wa nisisiyi, leti ita Tinubu ni o wa.

Ọkan ninu awọn oguna gbongbo dokita Oyinbo igbana, Dokita Grey jẹ enikan ninu awọn ti o da ibi iṣẹ yi silẹ. Ologbe Dokita Oguntọla Sapara ko ibẹ ṣe'rẹ lati mọ tọka fun awọn aboyun.

## Moto Ayokele

Ile awọn Oyinbo ọlọkọ-oju omi ti a npe orukọ wọn ni Elder Dempster Lines ni ile ti o tun jẹ pataki ni Ẹhingbẹti ti a ba ti kuro ni ti awọn Oyinbo onisọwo ti mo sọ wipe a npe orukọ wọn ni Lagos Stores tabi "Ankuri Magani Dunia".

Ọkan ninu awọn Oyinbo ọlọkọ oju omi yi ni o kọ gbe mọto ayọkẹlẹ de Eko.

Ninu awọn Oyinbo onisowo pataki ọkan ni awọn G. B. Ollivant jẹ ni ilẹ Nigeria. Ile iṣowo wọn ni Ẹhingbẹti ni o gbe ile awọn Oyinbo Elder Dempster ti nwọn ntun kọ ti awọn BEWAX wa nibẹ nisisiyi. Awọn Oyinbo yi ni aṣọ iwọ-gbele, awọn aṣọ bi teru (calico) aṣọ itẹkọ, lọwọ pupọ fun tita. Mo gbọ wipe awọn Oyinbo onisowo yi ni o kọ ni ile-itaja ni ilu Abẹokuta.

## African Oil Nuts

Awọn Oyinbo ti a npe ni Afican oil Nuts yi nkan bi epo-pupa, ekurọ, epa ati koko (cocoa) ni nwọn tẹra mọ latima ra ni aiye atijọ ki nwọn to da iṣe owo wọn pọ mọ UAC. Nibiti ile iṣẹ wọn wa l'Ẹhingbẹti ni nwọn kọ ile ifowo pamọ Barclays Bank si lẹba Williams Street l'ẹgbẹ Shell Coy.

Awọn Oyinbo onisowo ti ibi iṣẹ wọn tun ṣe pataki ni Ẹhingbẹti yi ni Paterson Zochonis (P.Z.) Oyinbo Alagbọn ati C.W.S. Ile ti awọn Oyinbo Alagbọn gbe wa na ni nwọn wa di ọjọ oni, ti awọn C.W.S. ni awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun fi kọ ile ifowo pamọ Cooperative Bank leti Ṣọsi Alagogo (Christ Church Cathedral).

## Nigeria Motors

Lẹhin ile awọn Oyinbo C.W.S. ni ile awọn Oyinbo ti o kọ ntun mọto ṣe gbe wa, a si npe orukọ wọn ni Nigeria Motors. Bi o ba ra mọto lọwọ wọn bi o ba bajẹ nwọn a si ba ọ tunṣe. Owo-ọya wọn ko pọ pupọ nigbana. Owo ti nwọn nra mọto paapa ko tilẹ pọ.

Enia-dudu kan ti o ba wọn fi aga gba aga ninu iṣẹ mọto yi ni Ologbe W. A. Dawodu ni Daddy Alaja Street, l'Eko; awọn mọto ayọkẹlẹ ti nwọn wa nigbana ni FORD ati Willys Knight. Awọn mọto akẹru ni Reo, Ford Brockway ati Denby.

O fẹrẹ jẹ wipe ilu Amerika ni nwọn ti nko gbogbo awọn mọto yi wa nigbana; gbogbo epo-mọto inu panu garawu ni nwọn nrọ wọn si.

Mẹta ninu awọn mọto akẹru ti mo darukọ yi, awọn bi REO, BROCKWAY ati DENBY, bi enia ba ri wọn a mọ wipe ẹru ni wọn; nwọn ni agbara, nwọn si tobi, ẹru ni nwọn nfi awọn mọto yi ko nigbana. Ọkọ reluwe ni awọn enia nwọ pupọju, awọn ilu ti ọjuirin ko si ni mọto ta nibẹ.

## Awon Kora

Nigbati awọn enia alawọ-funfun kan ti a npe ni KỌRA kọ de si Eko ni eti odo ọsa ni Ẹhingbẹti ni nwọn kọ isọ ọja ti nwọn nta si Ọja ti nwọn nta na ni ilẹkẹ kan ti nwọn npe ni CORAL BEADS. Orukọ awọn enia alawọ-funfun yi kiṣe Kọra, awọn ara Eko ko gbọ ede wọn, ṣugbọn nwọn ri pe nwọn ma npolowo ọja wọn bayi: Kọra! Kọra!! Kọra!!! iyẹn ni wipe, "ẹ wa ba wa ra ilẹkẹ Coral". Eyi ni o jẹ ki awọn ara Eko sọ wọn ni Kọra di ọjọ oni.

Ti a ba nsọrọ nipa iṣẹ owo ṣiṣe l'Eko ko yẹ ki a fi ẹwọ rọ awọn ara ilu Syria ati Lebanon ti a npe ni Kọra yi danu nitoripe nwọn ṣe bẹbẹ lode Eko lori owo ṣiṣe.

Diẹ ninu awọn ti orukọ wọn kọ tan kalẹ ninu awọn Kọra na ni awọn bi Ologbe Michael Elias (eniti awọn ara Eko npe ni Aliyu), Joseph Minaise, Chargoury, Chidiac, Coury, Nahman, Abdallah, R. Saidi, Ferris George, Younes, Michael Atrib ("Dogo") Saliba, Fawaz, D. Mustapha, Nabhan ati Daboul.

Awọn Kọra yi ni o kọ bẹrẹ a nlọ ko ẹran malu lati Kano wa ta ni Eko. Orukọ ti a tun fun wọn nigbati nwọn bẹrẹsi fi mọto ṣe iṣẹ-aru (transport business) ni YALA–YALA. Tọsan toru, nwọn kii sun ti nwọn ba nfi mọto ko ẹru bọ wa si Eko lati ilu Oke nwọn a mọ sọ bayi fun awọn awa-mọto wọn YALA, YALA, iyẹn nipe, sare, sare ki o fina sii. Ọpọlọpọ enia ni o ma mbẹru lati ba wọn ṣe iṣẹ.

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370.

VOL XIV. No. 828. SATURDAY JULY 21,- JULY 27, 1962.


# Inu Ewu NI A WA

NI aise iye meji a mọ wipe gbogbo nyin ni o ti ka iwe irohin wa ti ọsẹ ti o kọja nipa baba onimọto kan ti o sọ ọmọdebirin ọmọ ile-iwe di odi, ati bi o ti wa ọmọ yi lọ si ile rẹ ti o ni on fẹ fa'ri fun un.

Lati ẹnu nkan bi ọdun mẹta sẹhin wayi ni a ti ngbọ orisirişi itan bayi nipa awọn enia buruku ti nwọn nfẹ fi ọmọ-ọlọmọ şẹ'şo. Ọrọ na jọ gate, ko jọ gate sugbọn o fi ẹsẹ mejeji tẹlẹ. L'oni a gbọ wipe nwọn pa baba oni-baba kan nwọn yọ nkan lara rẹ. Ọla a gbọ wipe nwọn mu ọmọ "danasungbo" lọ si igbo-imalẹ, alọ ni a ri, a ko ri abọ rẹ mọ.

Okiki irufẹ iwa bayi pọ tobẹgẹ ti nwọn fi sọ awọn kan (ti nwọn fura si wipe irufẹ iwa buruku bayi pọ larin wọn) ni orukọ "ọmọ-meji da owo silẹ." Iyẹn ni ọmọ-ọlọmọ ti nwọn fi gun ọşẹ-awure ti nwọn nji sa ni owurọ.

## Isale Oro L'egbin

Nitotọ ko si ẹniti ko fẹ ni owo lọwọ, sugbọn ọna ti o tọ suna ni o yẹ ki a gba lati ma fi wa a. Bi a ba şe owo pẹlu inu mimọ a ni lati jere işẹ ọwọ wa.

Nwọn ni isalẹ ọrọ l'ẹgbin. Bi a ba yẹ idi awọn ti o nşe işẹ buruku yi wo, a o ri wipe awọn ni nwọn nda'wo pupọ ninu Mọsalasi, awọn ni JAKA wọn npọ loşoşu, awọn ni ki fi owo-apo-alufa şere ninu ijọ Şọsi, sugbọn ỌRUNMILA, Ọrun-ni-o-mọ-ẹniti-yio-la ni ọjọ igbende Alukiamọ gẹgẹbi ọrọ awọn Imale.

Awa Eleti–Ọfẹ kesi awọn ọlọpa wa, ki nwọn jọwọ ki nwọn ma şe awọn baba onimọto alanu ti o ngbe ọmọ wo nidi mọto nibikibi. A si tun kesi ẹnyin obi, ki ẹ şe ikilọ fun awọn ọmọ yin.

Inu ewu ni a wa.

# Iwe Si Olotu

## Gbogbo Wa Ni Yio Jiya

Ọrọ ti o de si gbogbo awa Yoruba ni Ibadan kişe ẹjọ Awolọwọ, kii si şe ẹjọ ti Akintọla, gbogbo awa Yoruba ni ọrọ na bawi; gbogbo wa ni ao si jẹ iya na tọmọ tọmọ, ti a ko ba ro ori wa wo, ki a tete mọ nkan ti ao şe.

Gbogbo enia ti o wa ni Nigeria mọ wipe awọn Yoruba ni o ni Ilu Eko.

Nisisiyi ilu Eko na si ti bọ lọwọ nyin, ẹnyin Yoruba.

Nwọn tun ngba imọran apapandodo kan lọwọ-lọwọ nisisiyi ti nwọn yio fi Eko şe. Awọn Alabaşe ilẹ Yoruba (Mid West) nwọn tun fẹ ya wọn kuro lara yin. Ẹ ro ọrọ na wo, nitoripe ọmọ ale ni fi ọwọ osi juwe ile baba rẹ.

Ko nşe Awolọwọ, kişe Akintọla, ni ọrọ yi ba wi gbogbo wa ni yio jẹ iya na.

Emi ni

Ọmọ Abati

## A Nfe Ofin L'ori Awon Dokita Ijoba

Inu mi dun pupọ latika ọrọ yin ti ọsẹ yi ninu iwe Eleti-Ọfẹ ti ẹ sọ wipe ofin ti awọn oşelu Ijọba Ipinlẹ Ila orun fẹ şe, lori awọn dokita ijọba ti o tun nşe apamọ-pamọ işẹ abẹle, na dara pupọ.

Ko yẹ wa si nkan ti o mba awọn olotu Ijọba wa lẹru lati fọwọ si iru ofin bayi fun anfani awọ nara ilu.

Işẹ dokita işẹ alanu ni, sugbọn bẹkọ lori lọdọ awọn dokita ti wa. Ni ilu awọn Aganyin, Dokita Nkrumah ti şe ofin wipe on ko gbọdọ ri dokita ti o ba wa labẹ Ijọba nọ ki o mọ şe apamọ-pamọ işẹ abẹle nitoripe iyẹn ko ni jẹ ki nwọn fi tara tara şe işẹ-anu ti a gba wọn si.

Ẹ jọwọ ẹnyin olotu Ijọba wa ẹ gba wa lọwọ awọn dokita ti ko ni anu, ti nwọn fi ile-iwosan şe owo. Ẹ şe ofin lori wọn ki nwọn ye şe işẹ apamọ-pamọ,

Emi ni,

J. Ajala

Agege

# Baba Ti O Ta Omo Re Leru W'ewon

IKẸJA— Laipẹ yi ni Adajọ Kotu agba kan sọ ọdaran kan ti orukọ rẹ njẹ Salakọ Badiru, ẹni ọgbọn ọdun, atunkẹkẹ basikulu şe si ẹwọn ọdun marun nitoripe o jẹbi ẹjọ a-taọmọ-lẹru ti awọn Ọlọpa baa ro.

Awọn ọlọpa ni ninu ọdun ti o kọja, ọdaran yi mu ọmọ rẹ ti njẹ Isiaka, ọmọ ọdun mẹwa tọ Ọgbẹni kan James Akingbade lọ, ko mọ wipe ọlọpa ni Ọgbẹni Akingbade, o si ta ọmọ rẹ na ni ẹdẹgbẹta pọnun (£500).

Ọdaran yi ninn ẹjọ ti o ro fun adajọ ni ara abule Ikote lẹti Porto Novo ni on, o ni on ko ta ọmọ on lẹru rara, o ni işẹ ni on ran si atunkẹkẹ şe ọrẹ on kan.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ifaa Ki Pa Enia

AYILUKA tun de o! mo gbọ wipe awọn ọrẹ meji ti bẹrẹsi ja lori ogun ẹgbọn wọn ti ko ti jalaisi ti nwọn gbe lọ si ile Dokita Adekoye Majẹkodunmi. Olukuluku wọn ni nwọn nsọ wipe ẹru ẹgbọn awọn yi tọ si awọn lati fi ṣe ifaa jẹ; sugbọn ọrọ ifaa ki i pa enia, wahala ni o ma nko ba ni o. Boya ẹ ko mọ bi ọrọ ogun yi ti nlọ si ni Ipinlẹ Iwọ Orun, ma fi diẹ si eti nyin lọsẹ yi.

Ẹgbọn wọn ti o nṣe aisan na ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG). Ṣe enia ko le bi ọmọ ki ọmọ na ma ṣe igbona lọjọ kan, bi ko ba ṣe igbona ni ikoko lọjọ kan, a su'gbẹ ehin-huhu. Mo gbọ wipe igbona lati hu ehin oke-agba (wisdom tooth) ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre nṣe lọwọ nisisiyi, awọn ogunna gbongbo dokita ti nwọn mọ iru amodi yi wo si sọ fun mi wipe iru amodi bayi ki i pa enia, sugbọn o ma fi eti enia gbolẹ daradara ni.

## Wahala Lo Mu Wa

Awọn ibatan meji ti o fẹ pin dukia Ẹgbẹ Afẹnifẹre na ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ati ẹgbẹ alakee (NPC). Mo gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti iya wọn si loyun wọn sinu ni awọn paapa ni lati p'ẹjọ nitori awọn na ni ẹtọ ninu anpin ogun a-ko-pin ogun yi. Awọn ẹgbẹ na ni Ẹgbẹ Ọlọmọ tuntun (UPP) ti Oloye Akintọla fẹ dasilẹ. Nwọn ni awọn ko ti mọ bi ibeji ni iya ọmọ na a bi tabi ibeta, ki awọn le mọ iru ẹjọ ti awọn le pe nitoripe ti ọlọmọ kan lo ṣoro.

## Obe Tutu

Mo gbọ wipe Ọgbẹni Akinloye ti fẹsẹ si sokoto wipe nkan ti o ba gba ni awọn yio fun un, ninu eyiti o de ilẹ yi, on ni lati ri t'on ṣe ki on si ni ọmọlẹhin jaburata. Alhaji Bello, ọmọ Ọba Sokoto, ni ọrọ na ko le rara, sugbọn on a sọ fun ẹnyin ọmọ ODUDUWA wipe bi on ba ṣe adura ti on si gba awẹ tan ni Sokoto on a lọ ṣe iyoku ninu Mọsalasi Jimọh ni ilu Oyinbo.

Nitotọ o ti mu Ọba Katisina lọwọ ni ijẹsan ọjọ Jimọ ni gbogbo wọn mu asọ Alukimba ka ejika, nwọn lọ ṣe adura, nwọn si lọ ṣe akanṣe-adura ninu Mọsalasi Jimọ ti ilu London. Lẹhin eyi nwọn yan saka obi ati owo. Eyiti ẹnyin Yoruba Imale npe ni SAARA.

## Adamu Ntola

Sugbọn gbogbo wa mọ wipe Saraa l'ẹbọ Imale. Mo' mọ [Ọlọla Saudana Sokoto, Alhaji Bello (Ọbalọla). Mo mọ Ọlọla wa keji Alhaji Tafawa Balewa, Olotu Ijọba Apapọṣe Nigeria, awọn na si mọ mi daradara nitoripe nigbati gbogbo nyin ko ti mọ wọn gbogbo wa ni a ti ntẹ fada ni Wesley Street l'Eko ninu ile awọn ero kan ti nwọn npe ni Contineta1 Hotel lẹba Ṣọsi Baptist leti itẹ oku-igboro (Campos Square) l'Eko.

Gbogbo wọn ni nwọn bi daradara bi nwọn ti bi emi na nilu Ẹgba, sugbọn iyatọ ti o wa ninu ọrọ wa ni wipe omi odo OGUN ni emi mu lọjọ na lọhun pẹlu omi odo GBANGBA ni Agọ Ijaiye l'Abẹokuta. Emi ko mọ omi odo ti olukuluku awọn ọrẹ mi mejeji ti mo ti darukọ wọnyi mu; boya ti SOKOTO tabi ti BAUCHI tabi ti KADUNA ni, emi ko le sọ.

## Omo Oba Sokoto

Ọrẹ mi kẹta ti mo fẹ da orukọ rẹ lọsẹ yi ni Ọba Usuman Nagogo, Ọba Katisina, Ọlọla, akẹju ti ba ọmọrere jẹ. Mo ti mọ Ọba yi tipẹ diẹ nigbati o wa ni ọmọ ọba ki o to lọ si ilu Oyinbo pẹlu ọmọ baba rẹ kan. Nwọn ran wọn lọ si ilu Oyinbo nigbati ilu Oyinbo niyi, sugbọn awọn ọmọ-ọba ni lati gbadun aiye wọn, ko kuku si nkan ti o nmi wọn lọkan, owo wa, ọla si wa.

Ọrẹ mi, Ọba yi mọ ẹṣin gun, o si mọ ẹṣin lati fi ṣ'ere. O ko le pa layo ninu ere POLO ti wọn Oyinbo nma fi ẹṣin ṣe. A ki fi gbogbo ẹnu sọrọ tan. A si nj orin atijọ kan ti a mọ nkọ nipa awọn ọrẹ mi na bayi:

Ọmọ ọba Sokoto,
O Ti ṣe d'Awusa;
Ọrọ ana tajọ sọ,
Olofofo ti gbe lọ.

O ya mi lẹnu pupọ wipe Ọba Katisina tun le maṣe amugba lẹhin Ọmọba Sokoto lọ si ilu Oyinbo. Kayeti! bi aṣa awọn ara Ilọrin. Aiye nlọ, a ntọọ.

## Aiye Kotito

Mo ri iwe kan gba lati ilu Oyinbo ni ijeta wipe gbogbo iwe irohin ilu Oyinbo ni o ṣe apọnle Ọlọla Alhaji Belllo, Sarduna Sokoto, nigbati o gunlẹ si ọhun. Awọn iwe irohin kan ti a npe ni LONDON TIMES ni irọ ni pẹpẹ-npa ni ọrọ awọn ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) nibiti awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti Sarduna ti a npe ni NPC (ẹgbẹ Alakee) wa. Nwọn ni ẹnu awọn ẹgbẹ Alakee (NPC) yi ni o tolẹ nibikibi ni Nigeria.

Ọrọ re o, ẹnyin ẹgbẹ Alakukọ. Bi o ba jẹ wipe ẹnikan ni awọn iwe irohin ilu Oyinbo yi ṣe apọnle rẹ ni Ibadan, ori baba Ẹnugu a gbina. Kini ẹ wa ri sọ si ọrọ baba Kaduna ti nwọn npọle yi, ẹnyin ara Yaba? Mo gbọ wipe asiwere enia ni o ngbe Yaba ni aiye atijọ, ṣugbọn awọn ọlọgbọn oniwe irohin ti wa nibẹ,nisisiyi, ọrọ wọn lodi-lodi ni o mbọ si, iyẹn kiṣe ija. Ẹla ni ọrọ.

Mo gbọ wipe ko si nkankan ti o ta bi a npa irọ kakiri ni ilu Nigeria; mo gbọ wipe ọrọ irọ yi ta ju owo koko (cocoa) lọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun, a ni nwọn tilẹ npaṣẹ rẹ ni Oke Mapo ati lọdọ awọn oṣelu wa ni Itutaba ni ita Oje. Ọrẹ mi. kotilẹ nipe o ntin jinna ki o to ri awọn ti yio ra irọ lọwọ rẹ ni Ile Ifẹ tabi ni Ilesha tabi ni Ekiti. Ọgbẹni Ọshuntokun ti tun gbe tirẹ silẹ fun awọn ara Ekiti.

Mo gbọ wipe Ọshuntokvn sọkun nitori oju-ọna Ara Mọkọ, Igb ra Odo, Ọtun, Aiyede, Ijero, Ikarẹ, ati Ado Ilawe ti Oloye Awolọwọ ko tete ṣe ki awọn Awe le ri ọna mu ẹru iṣu wọlu fun iyan jijẹ ati pe lori ọrọ yi ni ija fi de. Ọrọ iyan kiṣe yẹyẹ lọdọ awọn Ekiti. Ọshuntokun ni o lọ, ara Ekiti ko lọ.

# ISINKU OLOYE OLOKORO DUN NI OGIDI

OGIDI KABA — Ni ọjọ kẹdogun osu kẹfa ọdun ni a gbọ iku Oloye Olokoro Olupeka ẹni ọgafa ọdun o si bi ọmọ merinlelogoji (44). Oloye yi jẹ ogunna gbogbo fun ijọ Ṣọṣi C.M.S. ni Ogidi: fun ọgbọn ọdun ni o fi jẹ Baba-ẹgbẹ gbogbo ijọ na ti o fi de Kabba - Ijumu ati Abunu-Akoko. Nigbati awọn ara ilu ri bi iwa rẹ tin nwọn tun fi jẹ Oye Ọlọda, lẹhin eyi nwọn sọ ọ di Olokoro ilu Okoro, nwọn si fi ọmọ rẹ si aiye rẹ.

Baba Ologbe yi ni o tẹ ilu ti nwọn npe ni Ilẹtẹju Ogidi do, gbogbo alej ti nwọn ba si koja nibẹ ni o ma nṣe ni alejo yato.

Ni Ṣọṣi St. John Ogidi ni nwọn gbe oku Oloye na lọ, ẹsẹ gbogbo enia pataki pataki ni o si pe si ibi isinku na. Alufa D.I. Ọiadugba pẹlu awọn Alufa S.A. Adeodu (lati Kabba) ati Alaboiuto Iyara, Ijumu lo ṣe eto - isinku na.

Diẹ niyi ninu awọn ti o wa si ibi oku na, Ọba ilu Ogidi, Ọba Ijumu, Igbẹde, Aee, Rise Egga Aye leẹfin awọn onisẹ Ọba Kabba pẹlu ọ̀pọ ọba, awọn Ọgbẹni S.M. Fedile, R.O. Dare, J.O. Adebola (lati Kabba); awọn Iyafin E.A. Ajọkẹ Ibitẹyẹ (lati Eko) Sareti lati (Kabba), Ebulu Iyawo Minisita Ajayi Kaduna. Orukọ awọn ti ko le wa ti nwọn fi iwe ki awọn ọmọloku niyi, Minisita S.A. Ajayi (Kaduna), P.S. Ibitẹyẹ (Eko) S.T. Ibitẹye (Kaduna), A. Dawodu, Ibadan, S.O. Alafiatayọ, Ẹde, C Ọbagunle (Eko), Maliki Ọlaj bu, Balẹ Eko-Ijumu, Iya'Tin Ọmọbọja Edu (Eko).

A ki awọn ọmọloku, awọn bi Baba-ẹgbẹ T. Olupẹka, Tiṣa M.A. Olupẹka, Iyafin Alice Adegbọro Ibitẹyẹ ati Rutu Faronbi ku Asẹhinde.

**E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ti O kun Fun Irohin Aladun**



## OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA ENITI O RA. BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

**ELETI--OFE DARABA**



# Dokita Nigeria Ntun Ise Ko Ni'lu

## OYINBO



DOKITA Wilson Onuigbo ni o wa ninu aworan yi ni ile ibiti nwọn gbe ti nyẹ kokoro arun wo ni ilu Oyinbo. Dokita yi ni on tun fẹ kọ iṣẹ si nipa arun kan ti nwọn npe ni Cancer ti o nṣe ọpọlọpọ enia lọsẹ. Ọdun marun gbako ni dokita yi fi ṣe iṣẹ ni ile-iwọsan Ẹnugu ni Ipinlẹ Ila orun.

## Ogbeni Moses Amadu Jalaisi

LOMẸ — Ọkan ninu awọn ọkawe Eleti-Ọfẹ ti o wa ni ilu Lomẹ, Ọgbẹni Moses Amadu jalaisi laipẹ yi ninu ile rẹ ni Lomẹ ni ilu Togo. Ọgbẹni yi jẹ ọkan ninu awọn ara Lomẹ ti o feran a nka iwe irohin Eleti-Ọfẹ lati ọdun pupọ s'ẹhin.

A ki awọn ẹbi rẹ lọkunrin ati lobinrin pẹlu ọmọ Ologbe na Ọkunrin, Joseph Amadu, pe awọn ku asẹhinde. Ẹlẹ oku a dara o.

# Cecil King And West African Press

LONDON—The growth of the newspaper industry in West Africa has been remarkable in the past decade. How has this happened? How is the West African Press supplied with news and how is a newspaper produced? The BBC African Service is presenting a radio feature about West African newspapers on Wednesday, July 25, written and narrated by John Stockbridge.

One of the best known newspaper groups throughout West Africa is the Mirror Group. It was the head of this British newspaper concern, Cecil King, who began publishing newspapers in West Africa at a time when locally owned papers were finding survival extremely difficult. Now the Mirror Group is nationally and regionally represented throughout Nigeria, Ghana and Sierra Leone.

In Wednesday's BBC programme Cecil King will be speaking about the growth of the newspaper industry in West Africa; listeners can also hear about the production of "West African Review" from the Editor, David Williams; and some of the staff of the London office of Overseas Newspapers will describe their job of supplying stories, features and pictures to the editorial offices in West Africa. Wednesday's BBC programme is part of the monthly series IN CONSTANT TOUCH.

## Americans Work Hard To Get Money: Aluko

NEW YORK—"Americans just aren't wealthy by accident, they worked for it," commented Dr. Samuel Aluko, Assistant Professor of Economics at the University of Ife, after spending four months traveling and studying in the United States.

Dr. Aluko, who recently left New York for Nigeria, indicated that he was also impressed by the "amount of respect for manual labour and the pride of doing a job" which he saw in America. He was very much interested in the mechanics for getting sales tax revenue from retail outlets to the Treasury.

The Nigerian educator was accompanied by his wife, Joyce, who also did medical social work in an American Hospital.

## 'Baths For Every Home'

LONDON—Tenants should be entitled to a bath, a hotwater system, and an inside toilet, and should be able to force landlords to provide these amenities, say 96 Labour M Ps. They tabled a Commons motion last night pointing out that only one out of every 200 landlords has applied for the State improvement grant designed to bring old houses up to date. They ask for legislation laying down that landlords of property good for another fifteen years be compelled to apply for an improvement grant.

An attempt will be made soon to force the Government to give a Commons reply to the demand.

**Read**

**And Advertise In the ELETI-OFE**

## Nigerian Teacher Meets Princess Margaret



Her Royal Highness Princess Margaret talking with Mr. A. Omonijo from Western Nigeria at a recent garden party given by Her Majesty's Goverment at Lancaster House, London, England.

The party was attended by teachers from the Commonwealth, training in Britain under the Commonwealth Bursary Scheme.

# Irohin Soki

LATI ỌWỌ AYILUKA

## Asiki-iwe

Bi oṣu yi ba pari, Ọlọla, Ọgbẹni Dokita Nnamidi Azikiwe, Gomina agba a lọ irin ajo ni gbogbo agbegbe Ipinlẹ Iwọ Orun; mo gbọ wipe nwọn ts bẹrẹsi palẹmọ fun un ni Abẹokuta, Ibadan, Ijẹbu-Ode, Ilesha ati ibi bẹẹbẹ ni Ipinlẹ na.

Mo gbọ wipe Oyinbo kii fi alarede si'lẹ ni Dokita Azikiwe fẹ ṣe t'ọn pelu Flọra. Nwọn a jọ lọ si irinajo na ni.

## Eko Ile

Nigbati iwe yi ba de ọwọ rẹ wa gburo wipe awọn Ọgbẹni wa, Oloye Obafemi Awolọwọ ati Samu Ladoke Akintọla ti de ilu Eko. Dokita Adekoye Majẹkodunmi ti o de wọn mọlẹsi dẹ okun ifaso won die, ẹ ni ki nwọn wa si Eko.

Mo gbọ wipe Oloye Awolọwọ a wa ni Ikẹja, Akintọla paapa a wa leti Ọdan l'Eko.

Awọn Ọlọpa a wa ni ọnn ọna wọn, nitorina ma ṣe ṣe wahala wipe o fẹ ri wọn, ṣugbọn gbogbo ọrọ Eko ile ni nwọn yio fi abọ si.

Awa Eleti-Ọfẹ, a ki nyin, ẹ ku abọ.

## Olowo Aiye

Ni ijẹrin Ọjọ'Ru ni Ọgbẹni wa, Oloye Okotie-Ebo (Olowo-sọ-oke-dilẹ) di ọmọ adọta ọdun ti nwọn bii si aiye. Gbogbo awọn enia pataki-pataki ni Oloye Olowo-sọ-oke-dilẹ na pe si ibi aṣeyẹ ọjọ'bi rẹ na.

A ki Oloye Okotie-Ebo ku ọdun ọjọ'bi yi. AYILUKA a ba nyin sọrọ ninu ọsẹ ti mbọ.

## Ibeji

Mo gbọ irohin kan lati ilu Oyinbo wipe Ọlọla Amadu Bello, Sardauna Sokoto, lọ si Mọṣalaṣi ilu Oyinbo ni ijẹsan ati pe lẹhin ti o kuro nibẹ o lọ si ile awọn alaisan kan ti nwọn npe ni Hammersmith Hospital lati lọ wo Hassani (Sukuta), ikan ti o ye ninu awọn ibeji aladapọ ti awọn bi ni oko Zaria.

Ọlọla Amadu paapa fi ọwọ lu aya, o si tun fi ọwọ lu ori ara rẹ wipe ki on na le bi ibeji tabi ibẹta tabi ibẹrin.

Ọlọla wa, adura a gba o, awa Eleti-Ọfẹ a wa si Sokoto lati ko gbogbo awọn ọmọ na jade.

## Ijebu De o

Mo gbọ wipe Oloye Akintọla gba iyi ati ẹyẹ lọwọ awọn ara Ijẹbu-Ode titi ti o fi de ilu Omu; gbara ti nwọn ti gbọ wipe nwọn da silẹ wipe ki o mu bọ wa si Eko ni gbogbo awọn ara ilu ti a wi yi ti bẹrẹsi mu aṣọ leka wa si oju ọna-mọto lati da muso fun un.

Mo gbọ wipe awọn ara ilu Ijẹbu-Ode na ti da si meji, ọkan fun Akintọla, ikeji fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG). Ẹ mọ fi ẹgbẹ Ọlọmọ ṣere o, Oloye Akintọla ti di araba.

---

**ELETI-OFE**

KỌ IWE SI OLOTU ELETI-ỌFẸ NIPA NKAN TI O BA NDUN Ọ LỌKAN.

---

# Alakoso Liberia Ati Oba Ilu Oyinbo



Aworan Ololа Alakoso ilu Liberia President Tubman ni e nwo yi, on ati Alaiyeluwa Elizabeth, Oba ilu Oyinbo ninu keke-eye ti nwon jo wo ni ilu London nigbati Alakoso Liberia gunle si ilu Oyinbo, on lati iyawo re fun abewo ilu na,

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370: OLOTU: OLA ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos,